# A YAN JOSẸFU SI IPÒ GÍGA

**Gẹnẹsisi 41:37-57**

**ẸKỌ 36 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Emi ti wà li ewe, emi si dagba; emi kò ti iri ki a kọ̀ olododo silẹ, tabi ki iru-ọmọ rẹ̀ ki o ma ṣagbe onjẹ" (Orin Dafidi 37:25).**

### Ifihan Lati Ọdọ Ọlọrun

Ọgbọn Josẹfu jọ Farao loju. O gba itumọ ti Josẹfu sọ fun ala rẹ, o si fara mọ ọn pe ohun ti o dara ni lati pese silẹ fun awọn ọdun iyan ti o n bọ lẹyin awọn ọdun ọpọ. Farao ọba Keferi yii fi ọgbọn han ninu iwa rẹ ju ọpọlọpọ eniyan lọ lode oni. Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa nipa idajọ ti o n bọ lori ayé; o si ti fun wa ni ami nipa awọn ọpọlọpọ nnkan ti yoo maa ṣẹlẹ ki Oluwa to de, ṣugbọn awọn eniyan kọ̀ lati bá Ọlọrun laja. Nigba ti wọn ba duro niwaju Rẹ̀ ni Ọjọ Idajọ, ki yoo si awawi, nitori Ọrọ Ọlọrun ti fun ẹlẹṣẹ ni ikilọ ti o pọ̀, O si ti fi awọn oloootọ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ṣe aloore lati maa kede ikilọ fun awọn alaiwa-bi-Ọlọrun nipa iparun ti n bọ, ṣugbọn wọn kọ lati gbọran si ikilọ yii.

Ni igba aye awọn baba nla awọn eniyan ko ni Bibeli fun itọni wọn, nitori naa igba pupọ ni Ọlọrun maa n ba awọn eniyan sọrọ ninu ala, gẹgẹ bi O ti ṣe fun Farao. Nigba miiran Ọlọrun maa n ba awọn wolii sọrọ lọna bayii ati nipa iran: ṣugbọn ni igba ti wa yii Ọlọrun ti sọrọ nipasẹ ọmọ Rẹ̀, a si ni Bibeli gẹgẹ bi itọni wa (Heberu 1:1, 2). Lẹẹkọọkan Ọlọrun le mu ki awọn ọmọ Rẹ̀ la ala; ṣugbọn ọpọlọpọ eniyan wa ti wọn n lọ kaakiri ti wọn si n wi pe awọn ri iṣipaya pataki lati ọrun, wolii eke ni wọn, ala wọn ki si i ṣe lati ọdọ Ọlọrun. Iru awọn wolii bẹẹ wa ni akoko Mose. Ṣugbọn Mose sọ nipa imisi Ọlọrun pe, bi wọn ba la ala kan tabi wọn ṣe iṣẹ iyanu lodi si aṣẹ Oluwa, "Iwọ kò gbọdọ fetisi ọ̀rọ wolĩ na, tabi alalá na: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin ndan nyin wò ni, lati mọ̀ bi ẹnyin ba fi gbogbo àiya nyin, ati gbogbo ọkàn nyin fẹ́ OLUWA Ọlọrun nyin" (Deuteronomi 13:3). Bi a ba ni ifẹ fun ootọ ninu ọkàn wa, Ẹmi Mimọ yoo fi ohun ti O fẹ han wa, bẹẹ ni a ki yoo si tẹle awọn alala eke.

### A Gbé Josẹfu Ga

Farao woye pe Ọlọrun wà pẹlu Josẹfu, o si pinnu pe ko tun si ẹlomiran ti o sàn ju u lọ lati ṣe iṣẹ nlanla ti fifi ounjẹ ti o pọ to pamọ laaarin ọdun meje ọpọ fun itọju awọn eniyan ilẹ naa ni ọdun meje iyan ti yoo tẹle e. Awọn eniyan orilẹ-ède miiran paapaa n bọ wa ra ounjẹ ni Egipti nigba ti iyan naa ba mu ni ilẹ wọn.

Igba ire ti de fun Josẹfu. Kò tun ni jiya fun ikorira awọn arakunrin rẹ mọ́; ko tun ni sìn bi ẹru mọ́ tabi ki o maa joro ninu ọgba ẹwọn awọn ara Egipti. A sọ ọ di igba keji ọba ilẹ naa. Ninu ile Farao tikara rẹ Josẹfu le paṣẹ fun awọn eniyan nibẹ, wọn si ni lati gbọran si aṣẹ rẹ. Ẹnikẹni ko le "gbé ọwọ́ tabi ẹsẹ̀ soke ni gbogbo ilẹ Egipti" lai gba aṣẹ lọwọ Josẹfu.

Ẹwọn wura ti a fi wọ Josẹfu ni ọrun jẹ ami aṣẹ, oruka naa si le jẹ eyi ti o ni kalamu ti o fi n fi ọwọ si iwe aṣẹ. A fun Josẹfu ni aṣẹ lati maa fi ọwọ si awọn iwe ọba!

### Josẹfu Jẹ Oloootọ

Josẹfu si jẹ ọdọmọkunrin ti ọjọ ori rẹ kere si iru ipo ọla ti o ga ti a gbe e si yii, ṣugbọn eyi ko mu ki o gberaga. O jẹ oloootọ ninu iṣẹ ti a fun un lati ṣe. Ọlọrun si ran an lọwọ lati ṣe eyi ti o tọ. O ri ere gba fun ara rẹ pẹlu, ni ti eyi pe ọba fun un ni orukọ ọla, o fun un ni iyawo, ati laaarin ọdun meje a bi ọmọkunrin meji fun un. O ni lati jẹ pe ile rẹ jẹ ile alaafia, nitori o wi pe Ọlọrun ti mu oun gbagbe gbogbo ijiya oun ati ile baba oun paapaa. Nigba gbogbo ni Ọlọrun maa n san ere fun awọn ọmọ Rẹ̀ bi wọn ba jẹ oloootọ nigba ti wọn n la iṣoro kọja. "Iṣoro oju ọna ki yoo jamọ nnkan kan mọ́ nigba ti a ba de opin ọna naa."

### Ọ̀pọ̀, Lẹyin Eyi, Ìyàn

Ọlọrun mu Ọrọ Rẹ̀ ṣẹ gẹgẹ bi Josẹfu ti sọ tẹlẹ, ilẹ naa si so eso lọpọlọpọ a si ko ounjẹ jọ ni ilu kọọkan to bẹ ti ẹni kan ko le sọ bi o ti pọ to.

Lẹyin eyi ni ọdun meje iyan naa de, wo o bi ipọnju naa i ba ti pọ to bi o ba ṣe pe ko si imura silẹ! Wò o bi igba naa yoo ti buru to fun awọn ti o kuna lati mura silẹ lati pade Ọlọrun wọn! Wọn yoo mọ nipa igbadun awọn olododo, ṣugbọn fun wọn ki yoo si ohun miiran bi ko ṣe ẹkun, aro, ati ipayinkeke.

A ti kọ ọ pe nigba ti Ọlọrun pe Abrahamu jade lati ilẹ abọriṣa ti O si fi idi rẹ kalẹ gẹgẹ bi baba orilẹ-ède titun kan ti O le pe ni ti Rẹ̀, O fi apẹẹrẹ kan lelẹ. Abrahamu mu ipa ti rẹ ṣẹ ninu eto naa; lẹyin eyi ni Isaaki de ati nikẹyin Jakọbu. Ọlọrun ti ṣeleri pe Messia naa yoo de lati idile Abrahamu, titi de ihin yii eto naa ko ti yi pada.

Ọlọrun ri i pe iyan nlanla kan n bọ̀ lori gbogbo ilẹ aye, ebi yoo ha pa awọn eniyan ayanfẹ Rẹ̀ kú? Ki ni yoo ṣẹlẹ si eto Rẹ̀? Ṣugbọn Ọlọrun mọ ohun gbogbo. Oun ki yoo si jẹ ki ohunkohun di iṣẹ Rẹ̀ lọwọ.

**A Pa Israẹli Mọ́**

Boya kò si orilẹ-ède miiran ti ilẹ rẹ lọra to lati mu ounjẹ jade ti yoo to lati fun awọn eniyan ni ounjẹ ni ọdun meje iyan naa. Nitori eyi ni Egipti, ni Ọlọrun pese ibi kan ti yoo jẹ iranlọwọ fun awọn eniyan Rẹ̀ lati mu wọn wa laaye, O si la ọna kan silẹ fun wọn lati lọ sibẹ.

Ko si ẹni ti o lero pe tita ti a ta Josẹfu si Egipti jẹ apa kan ninu eto Ọlọrun lati dá ẹmi awọn eniyan ayanfẹ Rẹ̀ sí nigba ti o dabi ẹni pe a o pa wọn run patapata. Wò o bi Ọlọrun ti kun fun inu rere to si awọn eniyan Rẹ̀! "Ã! ijinlẹ ọrọ̀ ati ọgbọ́n ati ìmọ Ọlọrun! awamáridi idajọ rẹ̀ ti ri, ọ̀na rẹ̀ si jù awari lọ!" (Romu 11:33).

**AWỌN IBEERE**

1. Njẹ Farao mọ pe Ẹmi Ọlọrun wà ninu Josẹfu?
2. Ki ni Josẹfu ṣe lati má jẹ ki ìyan wà?
3. Farao wi bayii fun awọn ara Egipti pe, "ohunkohun ti o ba wi fun nyin ki ẹ ṣe." Ta ni ẹni ti o sọ iru ọrọ bẹẹ ninu Majẹmu Titun?
4. Ki ni ṣe ti Farao pe Josẹfu lati wa tumọ ala rẹ̀?
5. Njẹ ala Farao ṣẹ gẹgẹ bi Josẹfu ti tumọ rẹ̀?